# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## ÀMÌ KAINI

## Ìtàn ...

**Genesisi 4:1-15**

Ìwà àti ìṣe àwọn ọmọ Adamu ati Efa mejeejì yàtọ̀ sí ara wọn. Kaini jẹ́ àgbẹ̀ aroko, to si ma nkọ́ ilé, ṣùgbọ́n Abẹli fẹ́ràn lati maa yi òkè kiri ati ẹ̀bá odò pẹ̀lú awọn aguntan rẹ̀.

Lẹhin ìgbàtí ẹ̀ṣẹ̀ ti wọ ayé titun yi nitori àigbọràn Adamu ati Efa, Ọlọrun wá gbé ètò ẹbọ rírú kalẹ̀, Ó sì ṣe àlàyé fún wọn pé laisi ìtàjẹ̀ silẹ̀, kò sí idariji ẹ̀ṣẹ̀ (Heberu 9:22). Ọlọrun wí fún wọn pé, ẹbọ yií yio tẹsiwajú títí di ìgbà ti Jesu yio wá lati kú gẹ́gẹ́ bi Ọdọ́-Aguntan Ọlọrun fun ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ayé. Abeli si fi otitọ́ inú mú ọ̀dọ́-aguntan kan wa sí iwájú Ọlọrun lati fi ṣe irubọ fun ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, ṣùgbọ́n Kaini rò wipé kò jẹ́ nkankan lati gbọ̀ràn sí àṣẹ Ọlọrun. Ó wo wípé ètò ẹbọ rírú jẹ́ nkan ìdọ̀tí, o sì rò pé bi oun ba sa ti mu nkan ẹbọ wá, ki oun si jọsìn sí Ọlọrun, pàtàki ẹbọ na ko jẹ́ dandan. Nitori náà, o mu ọrẹ ẹbọ lati inu iṣẹ́ rẹ̀ wá - díẹ̀ nínú rẹ̀ li o pèsè lati inu oko rẹ̀. Kaini sì rí bí iná ṣe ti ọrun sọkalẹ̀, ti o sì jó ẹbọ Abeli ti o si fi tirẹ̀ silẹ̀, nipaṣẹ ẹ̀yí, Kaini bínú gidigidi, o sì kún fún owú. Oluwa sì fi tìfẹ́tìfẹ́ rọ Kaini lati rẹ ara rẹ̀ sílẹ̀, kí ó sì gbọ̀ràn, ṣùgbọ́n Kaini tẹsiwajú ninu ọ̀tẹ̀ rẹ̀. Abẹli pẹ̀lú sì ba ẹ̀gbọ́n rẹ̀ ronú, ṣùgbọ́n Kaini fa ìbínú yọ. Ni ìgbàtí ara rẹ̀ yoo fi balẹ̀, Kaini ti pa àbúrò rẹ̀, Abẹli. Ọlọrun sì fi kaini ré, nígbàtí Kaini sì ṣe àròyé ninu ọ̀rọ̀ rẹ̀,Oluwa sì fi àmì si i lára, pé kí ẹnikẹni maṣe pa Kaini nitori ìwà ìpànìyàn rẹ̀ yi, t'ó jẹ́ àkọ́kọ́.



Ìwé Ifihan sọ fun wa wípé, ni ìgbà ìkẹhìn, ogun yio dide laarin awọn Kristiani niti ìgbà ti o yẹ lati ma a jọsin ati bi o ṣe yẹ ki wọn má a ṣe ijọsin. Láìpẹ́, gbogbo ènìyàn ni a o fi èdìdí Ọlọrun tabi àmi ẹranko náà dá mọ̀.

## Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọnyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Tani a o pamọ́ ninu ìyọnu meje tó gbẹ̀hìn náà?
**Ifihan 7:3**
Wipe, Ẹ máṣe pa ayé, tabi okun, tabí igi lara, titi awa o fi fi _________ sami si awọn iranṣe Ọlọrun wa ni _________ wọn.
Àkíyèsí: Awọn ti o ba gba edidi Ọlọrun si iwájú orí wọn, li a o pa mọ́ nígbàti ìyọnu náà ba bẹ̀rẹ̀ (Orin Dafidi 91:7-11).

2. Kinni "èdidi" yi ti awọn olododo ní, li iwájú orí wọn?
**Isaiah 8:16**
Di ẹ̀rí naa, fi edidi di ______________ naa laarin awọn ọmọ-ẹhin mi.
Àkíyèsí: A rí èdidi Ọlọrun ninú òfin Rẹ̀. Èdidi jẹ ohun kan ti o nmú ìwé ti a kọ níyì, ati wípé o ma nní àwọn àmúyẹ mẹta: Orukọ, Ipò, ati Agbègbè. Apẹẹrẹ ni "Kirusi Ọba Persia" ninu Esra 1:1.

3. Èwo ninu awọn òfin mẹwa li o ni gbogbo ohun èlò èdidi ?
**Eksodu 20:11**
Nitori ni ijọ mẹfa li _________ _________ ọrun oun ayé, okun ati _________ gbogbo ti mbẹ ninu wọn, o si sinmi ni ijọ́ keje: nitori naa li OLUWA ṣe busi ijọ keje, o si yà a si mímọ́.
Àkíyèsí: Òfin kẹrin nikan li o ni gbogbo ohun èlò èdidi ninú: (ẹ̀) "Oluwa" - orukọ Rẹ̀ (ẹ̀) "dá" - Ipò Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí i Ẹlẹda, (é) "ọrun ati ayé, okun ati ohun gbogbo ti o wà ninu rẹ" jẹ́ - agbègbè Rẹ̀.

4. Kinni Ọlọrun fun wa gẹ́gẹ́ bi pàtàkì àmì agbara Rẹ̀?
**Eskieli 20:12**
Pẹlupẹlú mo si fun wọn ni ọjọ́ isinmi mi, lati ṣe _________ laarin t'emi ti wọn, ki nwọn ki o le mọ̀ pe emi ni OLUWA ti o yà wọn si mímọ́.
**Eskieli 20:20**
Ẹ sì bọ̀wọ̀ fun _________ mi; nwọn o si jẹ _________ laarin temi ti nyin, ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe emi ni OLUWA Ọlọrun nyin.
**Eksodu 31:13**
Ki ìwọ ki o sọ fun awọn ọmọ Israeli pé, Ọjọ isinmi mi li ẹnyin o pamọ́ nitootọ: nitori _________ ni laarin emi ati laarin nyin lati irandiran nyin; ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe Emi li OLUWA ti o yà nyin si mímọ́.
Àkíyèsí: Ọlọrun sọ kedere pé Oun fún wa ni ọjọ́ Isinmi gẹ́gẹ́ bi àmi agbára tí Oun fi dá ohun gbogbo tí Ó sì tún yà á sí mímọ́. O jẹ́ èdidi Rẹ̀, tabi àmì àṣẹ. Ọ̀rọ̀ yi "èdidi," "àmì," ati "ẹ̀rí ìdánilójú" li a ma nlò ni ipò ara wọn ninu Bibeli (fi Genesisi 17:11 wé Romu 4:11 ati Ifihan 7:3 pẹlu Eskieli 9:4).

5. Kinni ohun ti ẹranko kejì ninu ìwé Ifihan ẹ́é nfi agbára mu gbogbo ènìyàn lati gbà?
**Ifihan 13:16**
O si mu gbogbo wọn, ati kekere ati nlá, ọlọ́rọ̀ ati talakà, ominiọ́ ra ati ẹrú, ki a fi _________ kan fun wọn li ọwọ́ ọ̀tún wọn, tabi ni _________ wọn.

6. Kinni àmì ẹranko náà?
Àkíyèsí: A kọ́kọ́ ṣe àfihàn ẹranko náà ninu Ifihan ori kẹtala (ẹ́é) ninu ẹ̀kọ́ kẹtala (ẹ́é). Kinni àmì agbàra ati àṣẹ rẹ̀? Ọ̀nà to dara jù lati mọ àmì àṣẹ rẹ̀ li lati bèèrè lọwọ papasi tà-à-rà-tà. Ṣe àkíyèsí awọn ìpele wọnyi lati inu ìlànà Ẹatolìe:
ìbéèrè: Èwo ni ọjọ́ Isinmi?
ìdahun: Satide (ọjọ́ Abamẹta) ni ọjọ́ Isinmi
ìbéèrè: Kinni ìdí ti a fi nkíyèsí ọjọ́ Àìkú (Sunday) ní ipò ọjọ́ Abamẹta (Satide)
ìdahun: A nkíyèsí ọjọ́ Àìkú ni ipò ọjọ́ Abamẹta nitori pé awọn Ìjọ Ẹatolìe nfún Sunday ní ọ̀wọ̀ tó yẹ fún Satide.

Omiran ninu ọ̀rọ̀ ìlànà ni èyí:
ìbéèrè: Njẹ́ o ni ọ̀nà miran lati fi hàn pé Ìjọ náà ni agbara lati gbé ọdún kan kalẹ̀ ti yio sì di òfin.
ìdahun: Bí ó bá jẹ́ wípé kò ní irú agbára àtí àṣẹ bẹ́ẹ̀ ni, kò ní le è ṣe bẹ́ẹ̀, níti pé àwọn ẹlẹ́sìn sowọ́pọ̀ pẹ̀lú rẹ̀, kò ní le è ṣe eṣe fún un lati fi Sunday ti iṣe ọjọ́ kinni ọ̀sẹ̀ rọ́pò fun àwọn tó nkíyèsì, fún àwọn to nkíyèsí Satide, ọjọ́ keje, àyípadà tí kò ní àṣẹ ninu Ìwé Mímọ́.

Nitori náà papasi nsọ wípé, àmì agbára ati àṣẹ oun lo nmu kí Sunday (ọjọ́ Àìkú) di mímọ́ - ìyipada ti gbogbo awọn Kristiani fẹrẹ̀ gbà tán. (Wo akori "Kinni ibeere pàtàkì ti Papasi bi awọn kristiani léèrè?")

7. Njẹ́ a lè fi ojú rí ọ̀kan ninu àmì ẹranko náà tabi èdidi Ọlọrun bí?
**Heberu 10:16**
Ẹ̀yí ni majẹmu ti emi o ba wọn dà lẹhin ọjọ wọnni, li Oluwa wi, emi o fi ofin mi si wọn li _________, inu wọn pẹlu li emi o si kọ wọn si.
**Oniwaasu 9:10**
Ohunkohun ti _________ rẹ rí ni ṣiṣe, fi agbara rẹ ṣe e; nitori ti kò sí ete, bẹ́ẹ̀ni kò sí ìmọ̀, tabi ọgbọ́n, ni isà-òkú nibiti iwọ nrè.
**Eksodu 13:9**
Yio si ma ṣe _________ fun ọ li ọwọ́ rẹ, ati fun _________ irantí ti agbedemeji ojú rẹ, ki òfin OLUWA ki o le wà li ẹnu rẹ: nitori ọwọ́ agbara li OLUWA fi mú ọ jade kúrò ni Egipti.
**Isaiah 59:6,7**
Okùn wọn kì yio di ẹwù, bẹ́ẹ̀ni nwọn kì yio fi iṣẹ wọn bò ara wọn: iṣẹ wọn ni iṣẹ ikà, iṣe ipá si mbẹ li _________ wọn, Ẹsẹ̀ wọn sare si ibi, nwọn si yara lati tajẹ̀ alaiṣẹ̀ silẹ̀: _________ wọn èrò ibi ni; ibajẹ ati iparun mbẹ ni ipa wọn.
Àkíyèsí: kò sí ẹ̀yí tí a le fi ojú rí ninu àmì ẹranko náà tàbi èdidi Ọlọrun. Iwajú orí dúró fún ọkàn, ọwọ́ sì dúró fún àmì iṣẹ́. "Lórí ọwọ́" ati "laarin ojú" jẹ́ àmì kan ti a ṣàbà ma nlò ninu iwé mímọ́ fún èrò ẹnikan ati iṣẹ́ rẹ̀ (Eksodu 13:16; Deuteronomi 6:8; 11:18). Ènìyàn yio gba àmì ẹranko náà si iwajú orí rẹ̀ nípa yíyàn lati gbàgbọ́ pé ọjọ́ Àìkú (Sunday) ni ọjọ́ mímọ́ dípò òtítọ́ Bibeli. Ènìyàn yio gba àmì sí ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀ nipa siṣe iṣẹ́ ni ọjọ́ Abamẹta (Satide) tabí ki o ma a pa òfin ọjọ́ Àìkú (Sunday) mọ́ ní òde nítori ìrọ̀rùn - bi iṣẹ́, idile ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí o tilẹ̀ jẹ́ wípé àmì náà ko ṣe é fi ojú rí fún ènìyàn, Ọlọrun yio mọ ẹni tí ó bá ní èwo nínú àmì náà (1 Timoteu 2:19). Ní ọ̀rọ̀ kan, olúkúlukù yio sàmì sí ara rẹ̀. Bi mo bá bọ̀wọ̀ fún Ọlọrun tí mo sì fiyè sí ọjọ́ Isinmi Rẹ̀, Ọlọrun yio sàmì simí lára pé ti Oun ni mo jẹ́. Bi mo ba si nfiyèsí ọjọ́ Isinmi èké ti ẹranko náà, Ọlọrun yio sàmì sí ara mi, pé ti ẹranko ni mo jẹ́.

8. Bawo ni Jesu ṣe nmọ̀ pé ìránṣẹ́ Oun ni a jẹ́?
**Romu 6:16**
Ẹnyin kò mọ̀ pé, ẹniti ẹnyin ba jọ̀wọ́ ara nyin lọ́wọ́ fun bi ẹrú lati maa gbọ́ tirẹ, ẹrú ẹniti ẹnyin ba _________ tirẹ li ẹnyin iṣe, ibaaṣe ti ẹ̀ṣẹ̀ sinu ikú, tabi ti igbọran si ododo?
**Johannu 14:15**
Bi ẹnyin ba fẹ́ràn mi, ẹ o _________ òfin mi mọ́.

9. Njẹ́ ẹnikẹni ni àmì ẹranko náà lọ́wọ́lọ́wọ́ bayi?
**Ifihan 13:17**
Ati ki ẹnikẹni má le _________ tabi ki o _________, bikoṣe ẹniti o bá ni àmì orukọ ẹranko naa, tabi iye orukọ rẹ̀.

Àkíyèsí: Kò sí ẹni ti o ni àmì ẹranko náà bayi. Nigbati àmì náà bá di dandan, awọn ti wọn bá gba àmì ẹranko náà ni wọn yio ni anfaani lati rà tàbi tà. Ní àkókò náà, awọn tò npa ọjọ́ Isinmi Ọlọrun mọ́ yio ṣe bẹ̀ẹ̀ lati fi ẹ̀mí wọn wéwu (Ifihan 13:15), awọn ti wọn si yàn lati ba ọjọ́ Isinmi mímọ́ Ọlọrun jẹ́ ati awọn ti wọn gbé òfin ènìyàn lékè òfin Ọlọrun ni a o sàmì si lára lati fi wọn hàn pé Aṣòdì-sí-Kristi ni wọn. Gbogbo awọn ti wọn jẹ́ olootọ́ sí Jesu ati ọjọ́ Mímọ́ Rẹ̀ yio gba èdidi ògo Jesu, ti yio sọ wọ́n di tiRẹ̀ titi lai. Awọn ti kò pa ọjọ́ kankan mọ́, li a o ka mọ Asodi-si-Kristi (Matteu 12:30).

10. Kinni ohun meji ti agbára Asodi-si-Kristi pinnu lati yipadà?
**Danieli 7:25**
Oun o si ma sọ̀rọ̀ nla si Ọga-ogo, yio si da awọn ènìyàn-mímọ́ ti Ọga-ogo lágara, yio si rò lati yi _________ ati _________ padà; a o si fi wọn le e lọ́wọ́ titi fi di ìgbà akoko kan, ati awọn akokò, ati idajì akókò.

Àkíyèsí: Danieli í fihàn pé, ṣe àfihàn àpèjúwe agbàra Aṣòdì-sí-Kristi ti Majẹmu lailai. O fihàn gbangba pé yio gbìyànjú lati yi òfin Ọlọrun àti àkókò padà. Papaẹy ti gbìyànjú lati yí òfin Ọlọrun padà nípa: (1) yíyọ òfin kejì kúrò lòdì sí ọ̀wọ̀ yíyá ère, (2) dídín òfin kẹrin lati ọ̀rọ̀ mẹrinleni-áàdọrun (94) kù sí ọ̀rọ̀ mẹjọ (8) ní ọ̀nà ati dènà dídarukọ pé èwo ni ọjọ́ Isinmi, àti (3) pípín òfin kẹwa sí òfin mejì. Papaẹy fẹ́ yí àkókò Ọlọrun padà nípa: (1) kíkọ́ àwọn ènìyàn lati dá ọjọ́ kini ọ̀sẹ̀ mọ̀ fun ọjọ́ Isinmi dípò ọjọ́ keje, àti (2) síṣe àwòkọse pagan Romu lati maa bẹ̀rẹ̀ ọjọ́ kọọkan ní òru dípò ìgbàtí oorun ba wọ̀.Àkókò Ọlọrun fún ọjọ́ Isinmi bẹ̀rẹ̀ lati ìwọ oorun ọjọ́ Ẹtì (Friday) sí oorun wọ̀ alẹ́ ọjọ́ Àbámẹta (Saturday) (Lefitiku 23:32). Kò sí ẹ̀dá kan tó gbọ́dọ̀ gbìyànjú lati ba òfin tàbí àkókò Ọlọrun jẹ́ (Matteu 5:18).

11. Kinni àbùkù ti Ọlọrun rí nipa awọn alufa tàbí olusọaguntan àtijọ́?
**Malaki 2:8,9**
Ṣùgbọ́n ẹnyin ti yapa kúrò li ọ̀nà náà: ẹnyin ti mu ọ̀pọlọpọ kọsẹ̀ ninu _________ ; ẹnyin ti ba majẹmu Lefi jẹ, li OLUWA awọn ọmọ-ogun wi, Nitori náà li emi pẹlu ṣe sọ nyin di ẹ̀gun, ati ẹni àìkàsí niwajú gbogbo ènìyàn, niwọn bi ẹnyin kò ti pa ọ̀na mi mọ, ti ẹnyin si ti nṣe _________ ninu òfin.
**Hosea 4:6**
A ké awọn ènìyàn mi kúrò nitori aini ìmọ̀: nitori iwọ ti kọ ìmọ̀ silẹ, emi o si kọ ọ, ti iwọ ki yio ṣe alufa mi mọ: niwọ̀n bi iwọ ti _________Ọ̀ _________ Ọlọrun rẹ, emi pẹlu o gbagbe awọn ọmọ rẹ.



Àkíyèsí: Inú Ọlọrun si nbàjẹ́ nígbàtí awọn olusọaguntan Rẹ̀ ba npa mẹjọ tabi mẹsan mọ ninu òfin Rẹ̀, ti wọn si ntipa bẹ̀ẹ̀ mu ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ kọsẹ̀ nipa òfin Rẹ̀ pé kí wọn pa ọjọ́ Isinmi mọ́. Ni òtitọ́, gbogbo Ìjọ gba wípé kò si ẹṣẹ Bibeli lati gbe ara wọn lẹ́ṣẹ̀ pé ki wọn ma a ya ọjọ Àìkú (Sunday) sí mímọ́ ninu ẹ̀kọ́ wọn. Ó bani nínújẹ́ pé, gbogbo awọn onigbàgbọ́ ati Catolic ni wọn jẹ̀bi lati dúró níwájú ìtẹ́ idajọ́ Ọlọrun nítorí pé wọn sọ ọjọ Isinmi Bibeli nù! Ọlọrun funra Rẹ̀ fun wa ni ọjọ́ Isinmi bi àmì agbára Rẹ̀ lati dá ati agbára Rẹ̀ lati yà sí mímọ́ ati lati gbàlà (Eksodu 31:17, Esekieli 20:12). Njẹ́ ẹnikan le ba àmì mímọ́ yi jẹ́, eyítí ó dúró fun Ọlọrun nlá ti ọrun ati gbogbo awọn ti O dúró fun bí?

12. Báwo ni awọn tí Ọlọrun fi ṣe olórí ni atijọ ṣe ma nfi ọ̀wọ̀ fun ohun nlá ti òfin Rẹ̀?
**Hosea 8:12**
Mo ti kọ̀wé ohun pupọ̀ ti òfin mi si i, ṣùgbọ́n a kà wọn si bi ohun _________.

Àkíyèsí: Àkókò ko iti yípadà. Ọlọrun ti gbé ọjọ́ Isinmi, àmì nlá Rẹ̀, kalẹ̀ laarin òfin Rẹ̀ ati wípé O si bẹ̀rẹ̀ àṣẹ náà pẹlu ọ̀rọ̀ yi pé “rántí.” Síbẹ̀, loni ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ lo rò pé pipa ọjọ́-keje ọjọ́ Isinmi mọ́ jẹ́ nkan ajẹ̀jì.

13. Ní pàtó, kinni ọ̀wọ̀ ti Ọlọrun fun awọn olórí ẹlẹ́sìn nipa ọjọ́ Isinmi mímọ́ Rẹ̀?
**Esekieli 22:8**
Iwọ ti _________ awọn ohun mímọ́ mi, o si ti sọ ọjọ́ isinmi mi di aìlọwọ̀.
**Esekieli 22:26**
Awọn alufa rẹ̀ ti rú òfin mi, nwọn si ti sọ ohun mímọ́ mi di àìlọwọ̀: nwọn kò fi _________ saarin ohun mímọ́ ati àìlọ́wọ̀, bẹ̀ẹ̀ni nwọn kò fi ìyàtọ̀ hàn laarin ohun àimọ, ati mímọ́, nwọn si ti fi ojú wọn _________ kúrò li ọjọ́ isinmi mi, mo si di ẹni àìlọwọ laarin wọn.

Àkíyèsí: Ọlọrun ba awọn olórí ẹlẹsin wí, awọn to nsọ wípé ọjọ́ isinmi kò jẹ dandan, ti wọn si nsọ wípé “Bayi ni Oluwa wí” ti ki iṣe òtítọ́ si ri bẹ̀ẹ̀.

14. Ẹ̀ṣẹ̀ wo ni pàtó ni Ọlọrun pàṣẹ fun awọn olórí lati sọ ni gbangba pé ibi ni?
**Isaiah 58:1,13,14**
KE rara, máṣe dasi, gbe ohùn rẹ sókè bi ipè, ki o si fi irekọja awọn enìyàn mi _________ wọ́n, ati ile Jakọbu, ẹ̀ṣẹ̀ wọn, Bi iwọ ba yi ẹse rẹ kurò li ọjọ́ isinmi, lati má ṣe _________ rẹ li ọjọ́ isinmi mi; ti iwọ si pè ọjọ́ isinmi ni _________, ọjọ́ mímọ́ OLUWA, ọlọ́wọ̀; ti ìwọ si bọ̀wọ̀ fun un, ti iwọ kò hù ìwà rẹ, tabi tẹle afẹ́ rẹ, tabi sọ ọ̀rọ̀ ara rẹ: Nígbà naa ni inu rẹ yio dùn si OLUWA, emi o si mu ọ gùn ibi gíga ayé, emi o si fi ilẹ nini Jakobu baba rẹ bọ́ ọ: nitori ẹnu OLUWA li o ti sọ ọ.

Àkíyèsí: Ọlọrun pe awọn olórí níjà pé ki wọn pe àìpa ọjọ́ isinmi mọ́ ni ẹ̀ṣẹ̀ ati pé ki wọn ṣọ fun awọn ènìyàn Oun pé ki wọn o ma a pa ọjọ́ isinmi mọ́. Gẹ́gẹ́ bi ti awọn ọmọ ẹyin latijọ, ààbò wa tó dájú ni pé kí a ma gbọ̀ràn sí Ọlọrun ju ènìyàn lọ. (Iṣe Awọn Aposteli 5:29).

15. Nígbàtí o ba pinnu lati gba Jesu ati lati má a tẹle E pátápátá, kinni yio ṣẹlẹ̀?



**Matteu 11:29**
Ẹ gbà àjàgà mi si ọrùn nyin, ki ẹ si maa kọ́ ẹ̀kọ́ lọdọ mi; nitori oninu tutu ati onirẹlẹ ọkàn li emi: ẹnyin o si ri _________ fun _________ nyin.

Àkíyèsí: Isinmi ologo pẹlu alaafia wọ inú ọkàn rẹ ni ìgbàtí o bá yípadà. Ọjọ́ isinmi ti o túmọ̀ sí "isinmi" jẹ àmì isinmi ati alaafia ti o wá lati inu dídi àtúnbí (Heberu è:ẹ́ọ́ẹ̀ò). Gbogbo awọn ti wọn di atunbi ni tootọ yio pa ọjọ́ isinmi mọ́ gẹ́gẹ́ bi i àmì ìbùkún isinmi náà (kiyèsi ẹṣẹ è,ó,ẹ̀ò). Kò sí ayọ ti o dabí ayọ ti o ma nwá sí ọ̀dọ̀ ẹnitó yípadà t'o si npa ọjọ́ isinmi mọ́.

# Èsì Rẹ

Kí o tó le sọ pé “rárá” sí àmì ẹranko náà, o gbọdọ sọ pé “bẹ̀ẹ̀ni” si edidi Ọlọrun. Jesu ndúró ni ẹnu ìlẹ̀kùn ọkàn rẹ fún idahun rẹ. Njẹ́ o ṣetan bayi lati lọ si abẹ́ àsia ọjọ́ isinmi ologo Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bi idanilojú pé o ti gbà Á ni Ẹlẹda ati Olugbala rẹ?

ÌDÁHÙN:______________________

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ̀ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP14.indd 2
12/7/12 10:55 AM